Ẹ̀dà ọ̀fẹ́ ti Ìwé Ìbéèrè Òfin Iràǹlọ́wọ́ Owó, Ìsọníṣókí Èdè Tó Dán Mọ́rán, àti Òfin Ìdíyelé àti Gbígbà wà nílẹ̀ ní Èdè Gẹ̀ẹ́sì, Sipaniṣi, àti àwọn èdè míràn tó bá àmúyẹ tí a ṣàlàyé nínú Ofin Ìrànlọ́wọ́ Owó mu nípasẹ̀:

- Kíkàn sí Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ilé ìwòsàn Ẹ̀ka Ìforúkọsílẹ̀
- Pípe 281.243.1073 tàbí 281.243.1000, ẹ̀yàn 9
- Bíbéèrè fún ìwé ìbéèrè nípa í-meèlì: Attn: Financial Assistance 16906 Southwest Freeway Sugar Land, TX 77479
- Gbìgba ìbéèrè sílẹ̀ láti Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony: http://www.memorialhermannfirstcolony.com/financial-assistance-program/

## Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony

Láti rí bóyá o yẹ fún ìrànlọ́wọ́ owó, Medicaid, Medicare, tàbí àwọn ètò míràn, àti fún ìrànwọ́ ọ̀rọ̀ àṣírí lọ́fẹ̀ẹ́ láti béèrè, kàn sí:

**Àwọn Iṣẹ́ Ìṣòwò Aláìsàn**
Attention: Financial Assistance
16906 Southwest Freeway
Sugar Land, TX 77479

Fóònù: 281.243.1073 tàbí
281.243.1000, ẹ̀yàn 9

Ọjọ́ Ẹtì: 8 a.m. - 5 p.m.
Ọjọ́ Ajé - Ọjọ́bọ̀: 8 a.m. - 7 p.m.

Déètì Ẹ̀yà Oṣù ọ̀wàwà 1, 2018

MEMORIAL HERMANN

4412308-5/19

# Òwò aláìsàn Ìsọníṣókí Ìrànlọ́wọ́

## Ìsọníṣókí Èdè Tódán Mọ́rán



Àwọn Ìbéèrè Pàtàkì Tí A Dáhùn:

- Irú àwọn ìpèsè wo ni a ṣe?
- Báwo ni mo ti le béèrè fún ìrànlọ́wọ́?
- Tani ó yẹ fún ìrànlọ́wọ́?
- Kínni àwọn òdíwọ̀n owó-àpawọlé?
- Tí mi kò bá kójú ìwọ̀n fún òdíwọ̀n owó-àpawọlé ńkọ́?
- Níbo ni mo ti le rí ìwé ìbèrè láti le bèrè?

MEMORIAL HERMANN

# Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó (FAP)

Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony fún ni ní òwò ìrànlọ̀wọ́ fún àwọn aláìsàn tó yẹ tó dá lórí owó àpawọlé, ìwọ̀n ẹbí wọn àti Ìpele Ìṣẹ́ Ìjọba ìpínlẹ̀ fún ẹ̀dínwó pàjáwìrì díẹ̀ tàbí kíkún tàbí ìtọ́jú ilé ìwòsàn ètò ìlera tó yẹ. Àwọn aláìsàn tí ń wá ìrànlọ́wọ́ owó gbọ́dọ̀ béèrè fún ètò náà, èyítí a ṣe ìsọníṣókí rẹ sínu àkọsílẹ̀ yìí.

## Irú Àwọn Iṣẹ́ wo ni ó Kàn?

Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó (FAP) pèsè ààbò fún àwọn iṣẹ́ pàjáwìrì àti iṣẹ́ ìlera tó ṣe pàtàkì èyítí Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony ń pèsè.

Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó KÒ KAN: àwọn ìlànà òge, àwọn iṣẹ́ ni a pesè nípasẹ̀ Oníṣègùn àti àwọn olùpèsè tókùn tí wọn tọ́jú rẹ Ní Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony ṣùgbọ́n Ilé ìwòsàn náà kò gbàwọn síṣẹ́, Tàbí àwọn olùpèsè tí ó má sanwó yàtọ̀ sí Ilé ìwòsàn fún ìpèsè wọn

## Bí a ti le Béèrè

Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó àti Ìwé Ìbèrè ni a le fọwọ́ gbà, nípasẹ̀ í-meèlì, nípasẹ̀ ẹrọ ìbánisọ̀rọ̀ àti láti ojúlé wẹ́ẹ̀bù Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony Parí ìbéèrè náà, ṣàfikún àwọn ìwé àkọsílẹ̀ tí wọ́n bèrè kí o sì fàá kalẹ̀ sí Ẹ̀ka Iṣẹ́ ti Ìforúkọsílẹ̀ / Ìgbaniwọlé Ilé-ìwòsàn tàbí sí àdírẹ́sì tí a kọ sẹ́yìn ìwé-ìléwọ́ náà.

## Àwọn Òdíwọ̀n Owó-àpawọlé

Ọ̀kan nínú àwọn ohun àmúyẹ ni owó-àpawọlé tó dá lórí tàbílì ìsàlẹ̀:

| ÀWỌN ÌTỌ́NI ÀINÍ 2019 | |
|---|---|
| Àwọn ènìyàn tó wà nínú ẹbí/mọlẹ́bí | Owó-àpawọlé Lọ́dọọdún |
| 1 | $ 12,490 |
| 2 | $ 16,910 |
| 3 | $ 21,330 |
| 4 | $ 25,750 |
| 5 | $ 30,170 |
| 6 | $ 34,590 |
| 7 | $ 39,010 |
| 8 | $ 43,430 |

Fún àwọn ẹbí/mọ̀lẹ́bí tó ní ju ènìyàn 8 lọ: ṣàfikún $4,420 fún ẹni àfikún kọ̀ọ̀kan

## Tani ó yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó?

Iye owó fún ìrànlọ́wọ́ owó dá lórí owó-àpawọlé rẹ, ìwọ̀n ẹbí àti ìpele Àìní Ìjọba àpapọ̀. Àwọn aláìsàn tó ní owó-àpawọlé ẹbí tó jẹ́ 200% ti Ipele Àìní Ìjọba tàbí tó kéré jù bẹ́ẹ̀ lọ le yẹ fún ẹ̀dínwó 100%. Àwọn aláìsàn tó ní owó-àpawọlé ẹbí tó ju 200% ti Ipele Àìní Ìjọba lọ le yẹ fún ẹ̀dínwó.

Wo ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé nínú òfin náà ní:
**http://memorialhermannfirstcolony.com/financial-assistance-program**

Àwọn aláìsàn tó yẹ ni a ko ní díyelé mọ́ fún pàjáwìrì tàbí ìtọ́jú ìlera míràn tó ṣe pàtàkì ju Iye Tí A ń Bèrè (AGB) lọ́wọ́ àwọn aláìsàn tó ní ìdójútòfò.

Àwọn ọ̀nà ìdámọ̀ àwòrán wọ̀nyí ni a ń gbà fún ẹ̀rí ìdánimọ̀:

- Ìwé ìgbàláyè awakọ̀ ti ìjọba tàbí káàdì ìdánimọ̀
- Káàdì ìdánimọ̀ tí ọmọ ilé-ìwé
- Ìwé ìrìnà (US tàbí òkèrè)
- Ìwé ìrìn-àjò ti U.S.
- Káàdì ìdánimọ̀ èyítí Aṣojú Ìjọba Ilẹ̀ Òkèrè fúnni
- Káàdì Ìsanwó (pẹ̀lú fọ́tò)